## ÌFẸ́ ỌLỌRUN NÍNÚ AYÉ ÈNÌYÀN

Ọlọrun fẹ́ gbogbo ènìyàn, Ó sì fẹ́ kí gbogbo ènìyàn rí ìgbàlà.
Ìfẹ́ Ọlọrun sí gbogbo ènìyàn farahàn nínú ìgbé-ayé, ikú àti àjíǹde Jesu Kristi
**'Nítorí Ọlọrun fẹ́ aráyé to bẹ́ẹ̀ tí Ó fi Ọmọ bíbí Rẹ̀ kan ṣoṣo fúnni, pé ẹnikẹ́ni tí ó bá gbà Á gbọ́ ma ba à ṣègbé, ṣùgbọ́n kí ó lè ní ìyè àìnípẹ̀kun'** (Ihinrere ti Johanu 3: 16)

Òfin tí ó ga jù nínú Bíbélì nì yí:
**'Kí ìwọ fẹ́ràn Olúwa Ọlọrun rẹ pẹ̀lú gbogbo ọkàn rẹ àti pẹ̀lú gbogbo ẹ̀mí rẹ àti pẹ̀lú gbogbo agbára rẹ àti pẹ̀lu gbogbo òye rẹ; sì fẹ́ràn ẹnikejì rẹ bí ara rẹ'** (Ihinrere ti Luku 10: 27)

Olorun fún Mósè ní àwọn òfin mẹwa wọ̀nyí:

- **Èmi ni Oluwa Ọlọrun rẹ. Ìwọ kò gbọdọ̀ ní ọlọrun míràn pẹ̀lú mi**
- **Ìwọ kò gbọdọ̀ pe orúkọ Oluwa Ọlọrun rẹ lásán, nítorí Oluwa kò ní ṣe inúdídùn sí ẹnikẹ́ni tí ó bá lo orúko Rẹ̀ lásán.**
- **Rántí ọjọ́ ìsimi Oluwa, kí o sì yà á sí mímọ́**
- **Bọ̀wọ̀ fún bàbá àti ìyá rẹ**
- **Ìwọ kò gbọdọ̀ pa'nìyàn**
- **Ìwọ kò gbọdọ̀ s'agbère**
- **Ìwo kò gbọdọ̀ jalè**
- **Ìwọ kò gbọdọ̀ jẹ̀rí èké sí ẹnikejì rẹ**
- **Ìwọ kò gbọdọ̀ ṣe ojúkòkòrò sí ilé ẹnikejì rẹ**
- **Ìwọ kò gbodò ṣe ojúkòkòrò sí ìyà ẹnikejì rẹ, tàbí ọmọ ọ̀dọ̀ rẹ̀ ọkùnrin, tàbí ọmọ ọ̀dọ̀ rẹ̀ obìnrin, tàbí kẹ́tẹ́kẹ́tẹ́ rẹ̀, tàbí akọ màálù rẹ̀, tàbí ohunkóhun tí í ṣe ti ẹnikejì rẹ**

**A FIFẸ́ PÈ Ọ́ LÁTI DARAPỌ̀ MỌ́ WA NÍ ÌJỌ ONÍHÌNRERE TI LUTERANI**

Inú wa yóò dùn láti dáhùn àwọn ìbéèrè rẹ

Kirkon lähetystyön keskus, Helsinki 2003 (yoruba)



# ÀLÁFÍÀ

*Ọ̀rẹ́ Ọ̀wọ́n,*
*Ìjọ wa kí ọ káàbọ̀, a sì f'ìfẹ́ pè ọ́ láti jọ́sìn pẹ̀lú wa. Ní gbogbo ìgbà ni ìnfààní wà fún àwọn àlejò láti jọ́sin àti láti gbàdúrà nínú ìjọ wa*
*Ní gbogbo ọjọ́ àìkú (Sunday) ni a máa n pàdé nínú ìjọ wa ní aago mẹwa àárọ̀ (10a.m.) láti gbàdúrà àti láti sin Ọlọrun, láti gbọ́ ọ̀rọ̀ Rẹ̀ àti láti ní ìdàpọ̀ pẹ̀lú ara wa.*
*Gbogbo ènìyàn ni a pè sí àwọn ìsìn wọ̀nyí*

## DÍẸ̀ NÍNÚ KÓKÓ ÈSÌN KRÌSTÌÁNÌ

### ÌJẸ́WỌ́ ÌGBÀGBỌ́ / ẸJẸ́

Ìgbàgbọ́ krìstìánì nínú Ọlọrun kan ṣoṣo hàn nínú ìjẹ́wọ́ ìgbàgbọ́. Ọlọrun yi, tí í ṣe mẹ́talọ́kan, ni a mọ̀ ní Ẹlẹda, Olùràpadà àti Olùsọdimímọ́
**Mo gba Ọlọrun Baba Olódùmarè gbọ́, Ẹlẹda ọ̀run àti ayé:**
**Mo gba Jesu Kristi gbọ́, Ọmọ Rẹ̀ kan ṣoṣo Oluwa wa, Ẹniti a fi Ẹ̀mí Mímọ́ l'óyún, Ẹniti a bí nínú Màárià Wúndíá, Ó j'ìyà lọ́wọ́ Pontu Pilatu, Ẹniti a kàn mọ́ agbelebu, Ẹniti ó kú, tí a sì sin, Ó sọkalẹ̀ re ipò òkú, ní ọjọ́ keta, Ó jíinde kúrò nínú òkú, Ó re òkè ọ̀run, Ó sì joko lọwọ́ ọ̀tún Ọlọrun Baba Olódùmarè. Níbẹ̀ ni yóò ti ṣe ìdájọ́ ààyè àti òkú,**
**Mo gba Ẹ̀mí Mímọ́ gbọ́, ìjọ Ọlọrun l'àgbáyé, ìdàpọ̀ àwọn ènìyàn mímọ́, ìdáríjì ẹ̀ṣẹ̀, àjíinde ara kúrò nínú òkú, àti ìyè tí kò nípẹ̀kun.**

### ÀDÚRÀ ÀTI ÌJỌ́SÌN

Ìjọ́sìn wa ní orisirisi ẹ̀ka.
Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà ni a máa n ní ìsìn ìdàpọ̀ mímọ́
Àwọn ẹ̀ka pàtàkì nínú ìsìn wa ni wọ̀nyí:

| | |
|---|---|
| **Àdúrà** | **Ìdàpọ̀ Mímọ́** |
| **Kíka Bíbélì** | **Ìdúpẹ́ àti Ìyìn** |
| **Ìjẹ́wọ́ ìgbàgbọ́** | **Ìbùkún** |
| **Ìwàásù àti àdúrà** | **àwọn orin láti inú ìwé orín (5 – 6)** |

Nínú gbogbo ìsìn wa, a máa n gba àdúrà tí Jesu kọ́ wa

**Baba wa tí n bẹ ní ọ̀run,**
**Kí á bọ̀wọ̀ fún orúko Rẹ. Kí ìjọba Rẹ dé**
**Ìfẹ́ tìrẹ ni kí á ṣe l'áyé bí wọ́n ti n ṣe ní ọ̀run**
**Fún wa l'onje òòjọ́ wa lòní.**
**Dárí ẹ̀ṣẹ̀ wa jì wá, bí a ti n dárí ẹ̀ṣẹ̀ ji àwọn tí ó ṣẹ̀ wá.**
**Má fà wá sínú ìdanwò, ṣùgbọ́n gbà wá lọ́wọ́ ibi**
**Nítorí ìjọba ni tìrẹ́, agbára ni tìrẹ́, ògo ni tìrẹ láíláí. Amin**

### ÀWỌN SAKRAMENTI

Ìdàpọ̀ mímọ́ jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn sakramenti tàbí ayẹyẹ èsìn ní ìjọ Luteranì.
Sakramenti mìràn ni ìrìbọmi , tí Jesu fi lélẹ̀ pẹ̀lú ọ̀rọ̀ yi:
**'Nítorí náà, ẹ lọ sọ gbogbo orílẹ̀-èdè di ọmọ-ẹ̀hìn mi; kí ẹ sì máa ṣe ìrìbọmi fún wọn ní orúkọ Baba àti ti Ọmọ àti ti Ẹ̀mí Mímọ́. E máa kọ́ wọn láti kíyèsí gbogbo ohun tí mo pa láṣẹ fún yín'.**
(Ihinrere ti Matiu 28: 19 – 20)
Nípa ìrìbomi, ènìyàn á di ara ìjọ. Àgbàlagbà tí ó bá fẹ́ di ara ìjọ á gba idanilẹkọ lórí àwọn ohun tí ó ṣe kókó nínú ìsìn Kristiani àti ìgbé ayé kristiani, kí ó tó ṣe ìrìbọmi.
Àwọn ayẹyẹ mìràn nínú ìjọ wa ni ìgbéyàwó àti ìsìnkú

Àwọn àjọ̀dún ẹ̀sin kristiani rọ̀ mọ́ ìṣẹ̀lẹ̀ nínú ayé Jésù.
Àwọn àjọ̀dún tí ó ṣe pàtàkì jùlọ àti ohun tí wọ́n rọ̀ mọ́ ní wọ̀nyí:
**Kérésìmesì** – Ìbí Jesu
**Ọjọ́ Ẹtì (Friday) Rere** – Ikú Jesu lórí àgbéléèbú
**Àjíinde** – Àjíinde Jesu
**Ọjọ́ ìgòkè re ọ̀run** – Jesu gòkè re ọ̀run
**Ọjọ́ Pentikosti** – Ọjọ́ Ẹ̀mí Mímọ́ (ìdásílẹ̀ ìjọ Kristi)